# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORẸ AIYE TENI GBOGBO LAWA

No 1,426 WEDNESDAY AUGUST 11, 1965 (2D)


16 AUG 1965

## Okọ Ofurufu Kan Jalulẹ

VIETNAMESE:- Jinn jinni dabo gbogbo enia ti nwọn wa ninu ilu Vietnamse nigbati ọkọ ofurufu kan ti o ko awọn ọmọ ogun ti nwọn nja ninu i l e na nko awọn nkan ija ogun lọ si ibiti awọn gbe nja ti ọkọ ofurufu na si jalulẹ ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kejọ oṣu yi-

Irohin awọn ọlọpa ọ m o ogun inu ilu na fi ye wa wipe awọn bọmbu ati agba - etu pẹlu awọn nkan olero miran ni ọkọ ofurufu na ko, ṣugbọn bi ọkọ ofurufu na ti ṣe de ori oke ni awọn nkan na ba gbina ti awọn agba ati ibọn na si ndun fun rawon.

Ko pẹ pupọ lẹhin eyi ni ọkọ ofu rufu na ba gbina ti o si jabọ sinu ilu na ni gbogbo ilu ba gbojikan fun ariwo ti okiki si kan ku u.

Lẹsẹkẹsẹ ni gbogbo awọn ọmọ ogun ti nwọn wa ninu ilu na ti sare de lati wa ṣe anjo gbogbo awọn ọmọ ogun ti nwọn wa ninu ọkọ ofu rufu na, ṣugbọn gbogbo awọn mẹrinlelogun ti awọn wa ninu ọkọ ofu rufu na ni nwọn ku bamubamu ki ọkọ ofurufu na to de ilẹ.

Irohin na tun fi ye wa wipe ni arin ilu gan an ni ọkọ ofurufu na ja lule o si ba ọpọlọpọ awọn ile jẹ ninu ilu na.

# IJỌBA GBE ẸJỌ ỌRẸDẸIN KURO NI IJẸBU - ODE

IBADAN:- Gbogbo i l e palọlọ ti ẹsẹ ko si gbeji fun ogunlọgọ ọkẹ aimoye enia ti nwọn wa si ile ẹjọ giga Ibadan ni kutukutu owurọ ana ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kewa oṣu yi nigbati Ọlọla Adeyinka Morgan, Olori gbo gbo awọn adajọ Ipinlẹ I w ọ Orun Naijiria nsọ f u n gbogbo awọn enia ile ẹjọ na wipe, ki nwọn gbe ẹjọ Oloye Samuel Ọrẹdẹin, Alaiyeluwa Alfred Babington Asaye, Ologere Ọba ilu Ogere ati awọn enia meji la miran pẹlu wọn ti nwọn nṣe ni Ijẹbu—Ode kuro, ki nwọn si wa ṣẹ ẹjọ na ni ile ẹjọ giga Ibadan



Alaiyeluwa Babington Ashaye

Ọba Ilu Ogere [illegible]

Ninu idajọ rẹ eyiti o ṣe fun odidi iṣẹju marundinladọta, Ọ l ọ l a Adeyinka Morgan sọ fun gbogbo awọn enia ti nwọn wa sinu ile ẹjọ na wipe, nitootọ, ko ti si ẹjọ kan ti nwọn gbe kuro nibiti ẹjọ na ti ṣẹlẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria ri; ṣugbọn awọn gbọdọ gbe ẹjọ yi kuro ni Ijẹbu Ode nitoripe awọn nkan ko faramọ ni agbegbe na lati bi ọjọ mẹta.



Oloye Akin Olugbade



Olu Ayọọla

O tun so pẹlu wipe, ni ilu Ọba Oyinbo, India ati ni Ipinlẹ Ariwa, Ijọba a ma a gbe ẹjọ kuro ni ibiti nkan na ba gbe ṣẹlẹ lo ṣe nibomiran yatọ si ibiti ẹjọ na ti ṣẹlẹ.



Oloye S. T Ọrẹdẹin

Adajọ na tun ṣe ala ye wipe on gbọdọ gba ẹbẹ ti olori awọn agbẹjọro fun ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria mu wa si ile ẹjọ, Ọgbẹni Tajudeen Oki nitoripe enia mẹta ni nwọn ku ninu ilu na laipẹ yi.

Bi enia ba si ro gbo gbo ohunti n ẹlẹ ni Ijẹbu Ode oluwarẹ yio gba wipe koye ki awọn ṣe ẹjọ na ni Ijẹbu Ode rara fun alafia gbogbo awọn enia inu ilu naki rogbodiyan ati irukeru maa ba ṣẹlẹ ni u ilu na lẹhin ohunti wọn fẹ ṣe.

Adajọ agba na ti lẹ tun sọ ninu ọrọ rẹ wipe, yio lẹ iwa asiwere ati omugọ ti enia ko ba tẹlẹ ohunti ọkan ninu awọn ọga Ọlọpa sọ ni Ibadan nipa awọn ohunti nṣẹlẹ laipẹ yi.

Adajọ na tun sọ wipe, iwadi ẹjọ na ni nwon yio ṣe ni Ibadan ki iṣe ẹjọ na gan an ni on so wipe ki nwọn ṣe.

Irohin fi ye wa wipe nwon yio maa ba ẹ j ọ na lọ ninu ile ẹjọ giga Ibadan ni owuro yi nigba ti nwọn yio maa ba iwadi ẹjọ naalọ.

Nigbati nwọn bẹrẹ ẹjọ na ni owuro yi awọn enia ti Ijọba mba iṣe ẹjọ na ko wa sinu ile ẹjọ na.

Ṣugbọn gbogbo awọn agbẹjọro wọn ni nwọn wa ninu ile ẹ j ọ na ti nwọn si g b a ohun ti adajọ agba na sọ.

WO OJU EWE KẸFA



Ayọ Okusaga

# OLU AKỌWE IJỌBA GẸẸSI YIO DE SI EKO LONI

EKO:— Ni deede agogo mẹjọ kutukutu owurọ ana ọjọ Iṣegun ti iṣe ọjọ kẹwa oṣu yi ni Irohin de si ile iṣẹ wa lati ile iṣẹ Aṣoju Ijoba Gẹẹsi ni Orilẹ ede Naijiria wipe, Ọlọla Arthur Bottomey, Olu akọwe awọn ilẹ Okere fun Ijọba Gẹẹsi pelu Iyawo rẹ, Iyaafin Bessie Bottomey, ti iṣe akọwe rẹ yio ba ọkọ ofurufu de si Eko ni owurọ oni ọjọ ọjọ'Ru ti iṣe ọjọ kọkanla oṣu yi.



Iyaafin B. E. Bottomley

Irohin na tun ṣe alaye wipe, Ọlọla Bottomley ati Iyawo rẹ pẹlu awọn enia mẹrin miran ni nwon yio gunlẹ si ibudo ọkọ ofurufu Ikẹja ni deede agogo mẹsan abọ ni owurọ yi ninu Irinajo wọn si ilẹ awọn enia dudu.

Ọlọla Arthur Bottomley jẹ ọkan ninu awọn Minista ninu Ijọba Orile ede Ijọba Gẹẹsi, on si ni Minista Alamojuto eto awọn ilẹ ti o wa ni abẹ Ijọba Gẹẹsi ti nwọn si tun nba awọn Ijọba Gẹẹsi ṣe lẹhin ti nwọn ti gba Ominira tan.

Kii tun ṣe eleyi nikan ṣugbọn Ọlọla Arthur Bottomley ti jẹ ọkan ninu awọn Minista ti nwọn nṣe Ijọba Orilẹ ede Gẹẹsi ninu ọdun 1945 titi di ninu ọdun 1951.

## ILE IGBIMO

Ninu odun 1963, Ọlọla Arthur Bottomley ni nwọn yan ninu Ijọba Orilẹ ede Gẹẹsi lati maa sọrọ lori ohun gbogbo ti o ba ti jẹmọ awọn ilẹ okere ninu ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Gẹẹsi.

Awọn ti nwọn mọ itipa itan orilẹ ede Gẹẹsi fi ye wa ninu ile iṣẹ wa ni alẹ ana ni ọjọ kẹje oṣu kẹji ọdun 1907 ni nwọn bi ọlọla Arthur George Bottomley.

Nigbati o di ọmọ ọdun marun lo ti bẹrẹ si lọ si ilẹ ẹkọ, ṣugbọn nigbati o di ọmọ ọdun merinla lo jade ninu ile ẹkọ giga bi o si ti jade ninu ile ẹkọ na ni o ti bẹrẹsi ṣiṣẹ, ti o si tun ri iṣẹ rere ṣe.

Ṣugbon lẹhin igbati o ṣiṣẹ fun ọdun meji rere, o fi iṣẹ na silẹ, o si tun lọ bẹrẹ iṣẹ ninu ile iṣẹ awọn Oyinbo ọkọ relowe gẹgẹbi akọwe inu ile iṣẹ na.

Ṣugbọn ni gbogbo igbati o fi nṣiṣẹ ninu ile iṣẹ ọkọ reluwe yi, ọrọ na ko tẹ ọlọla Bottomley lọrun, ni o ba pinnu ninu ọkan rẹ pe, on yio tun lọ si ile iwe si, ni gbana ni o ba tun bẹresi lọ si ile eko nla ti Unifasiti, ti oba lọ si ibi iṣẹ ni alẹ, a lọ si ile ẹkọ ni owurọ.

Bayi ni ọlọla Bottomley bẹrẹsi ma ṣe titi ti o fi kọ iwe rẹ tan, ti fi pari iwe na ti o si jade.

Ṣugbọn ni gbogbo igbati Ọlọla Bottomley fi nlọ si Unifasiti yi, o fẹran lati maa kọwe ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ; on si ni nwọn yan gẹgẹbi akọwe ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ ninu ile iṣẹ ọkọ reluwe ni gbogbo igbati o fi nlọ si ile ẹkọ ti o si tun nṣiṣẹ nibẹ.

Bayi ni Ọlọla Bottomley nṣe nigbati o jade ni Unifasiti, o tun nṣe iṣẹ rẹ lọ ninu ile iṣẹ na. Ṣugbọn nigbati o bi ninu ọdun 1935, ni o ba fi iṣẹ silẹ ti o si gba isimi ifẹhinti kuro lẹnu iṣẹ patapata.

Lẹhin na ni o wa bẹrẹsi iṣe iṣẹ akọwe awọn ẹgbẹ oṣiṣẹ ti ko si tun ṣe iṣẹ na mọ ju eleyi lọ. On ni, o si nṣe eto gbogbo ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ bi nwọn yio ti ṣe maa gba owo gọbọi loṣu.

## OṢELU

Ṣugbọn ni gbogbo igbati o fi nṣe iṣẹ ẹgbẹ awọn oṣiṣẹ yi, o bẹrẹsi maa ni ifẹ lati maa ṣe ẹgbẹ oselu, nigbati nwọn si dibo ninu Ile Igbimọ Ijọba Ibilẹ, ilu Oyinbo o wọle ni ilu Ibo na, o si di ọkan ninu awọn ọmọ ile Igbimọ na.

Ṣugbọn bayi ni Ọlọla Bottomley ti nṣe awọn nkan rẹ diẹ diẹ ti ti gbogbo awọn nkan na si fi dara fun un. Nigbati o si di inu odun 1935 ni o ba ri Obinrin kan Omidan Bessie Ellen Wiles, awọn meji gba lati fẹ ara won ni nwon ba ṣe igbeyawo ninu odun na

Ninu ile Igbimọ Ijọba ibile na ni o wa titi di ọdun 1949, ni awọn ọmọ ile igbimọ na ba panu pọ e on ni awọn yio fi ṣe Meyo ilu Gyinbo, nwọn si yan an

Nigbati o di inu odun 1945, ni nwon ba yan ni alaga ile iṣẹ manamana, nwọn tun yan ni alaga ile Iṣẹ eto ọkọ, ile iṣẹ awọn panapana ati ti awọn ọmọ ogun ọkọ ofurufu ti nwon ma njagun loke.

Nigbati ogun bẹrẹ ninu odun 1939, ni awon ere ilu ba yan ni olori oko awon omo ogun, ti o si nṣe gbo-

WO OJU EWE KARUN



Ọlọla A. G. Bottomley
O. B. E., M. P.

# Iwe si Olotu Irohin Imọlẹ

## Eni-Ọwọ Atilade Kabọ O

*Mba ṣọpọ bi Olotu gbajumọ iwe Irohin-Imọlẹ ba le gba mi ni aye ranpẹ yi ninu iwe rẹ oloyin mọmọ lati ki Ẹni-Ọwọ Oniwasu E. A. Atilade ti o ṣẹṣẹ de lati ilu Ọba ni aipẹ yi.*

Gẹgẹbi mo ti jẹ ọkan ninu awọn ọmọ Akẹkọ ti o fẹran lati ma ka awọn iwe Atilade paapa ti o si jẹ pe on ni a fi kọ mi ni iwe alakọbẹrẹ nigbati mo wa ni ile Ẹkọ ti mo si ma ngbadun awọn iwe Ẹni-Ọwọ wa na, inu mi dun pupo nigbati mo gbọ pe oniwasu tun gba ẹbun ẹkọ ọfẹ lọ si ilu Oyinbo.



Ẹni—ọwọ Atilade

Ni idi eyi mo ki Ẹni-Ọwọ E. A. Atilade ku abọ irinajo rẹ Oluwa yio tun bọ ma ran ọ lọwọ, iwaju ni ẹ o ma lọ o!

A o tun ma rẹti awọn iwe re titun miran pẹlu oye titun ti ẹ ṣẹ ṣẹ gba o.

Emi ni
F. A. Oyerọgba
EKO

## Akiyesi Fun Omo Ilu Alla

Ẹjọwọ, ẹ ran mi lowo lati kesi awon omo ilu Alla ninu iwe nyin oloyin momo ti o tun nko 'ya ni ogbon ati oye.

Ọro mi na ni wipe, o ye ki a ma wa ilosiwaju ilu wa n asiko yi mo ni lati dupẹ lowo awon ẹgbẹ ti o njẹ "YMCS" tabi (Young-Men Christain Society) fun iṣẹ nla ti nwon nṣe fun ilosiwaju ilu Alla.

Gẹgẹbi a ti ngbo pe ina manamana ati ẹro soro Sokere yio wọ ilu Oro lai pẹ yi. mo bẹ awon ẹgbẹ ti mo darako yi ati awon ẹgbẹ miran ki nwon sa agbara nwon ki ina manamana ati ẹro isoro sokere ba le ya ni ilu wa.

Oluwa yio ran gbogbo omo Alla lowo amin. owo ẹnyin ẹgbẹ na yio mu roke o, amin.

Emi ni
Igbẹhin—Adun
ALLA

## Ẹ Ṣọra Pẹlu Ẹgbẹ Elẹtan

Olotu inu mi yio dun pupọ bi ẹ ba le gba mi ni aye ranpẹ ninọ iwo Irohin Imoọlẹ ti o nkọ wa ni ọgbọn ati oye lati kesi awọn ọmọ iya mi ni ọkunrin ati obinrin ki nwọn yara yago fun ẹgbẹ a'urọtọ bi elubọ.

Gbogbo wa ni a mọ ẹgbẹ na pe, ko wa alafia ati anfani awọn ọmọ Yoruba paapa awa ọmọ Ilawẹ-Ekiti ki ẹgbẹ D mọ ma pa irọ kun irọ, awa ọmọ Ilawẹ Ekiti kiṣe ọmọ ale, ọmọ ọkọ ni gbogbo wa.

Kosi ojulowo ọmọ Yoruba ti yio sọ pe ẹgbo Dẹmọ dara tabi pe ijoba ẹgbẹ Dẹmọ ro o in lọrun.

Inira ati wahala ni ẹsẹ ẹgbẹ Dẹmọ jẹ ni Ipinlẹ Iwọ Orun nitorina, ẹ ma gba irọ ẹgbẹ na gbọ.

Ẹ ku iṣẹ o olotu

Emi ni,
Samson Olu Akin
New Nigeria Shoes, EKO.


## Anfani Nla De Fun Gbogbo Awọn Ti Nlo Gulu

TI A FI NLẸ PAKO TABI IWE

Gulu Funfun eyiti a ti ṣe wa lati ilu Oyinbo ti o wa ninu Igo Funfun oorun rẹ dabi lọfinda ti a nbu sara Irohin ko to afojuba tete yara lọ ra tirẹ lodọ :
**Y, AROWOLO NI 118, Griffth Street, E. B Lagos**

| | | | |
|---|---|---|---|
| Igo kekere | 6/- | Igo Nla | 8/- |
| Igo mejila nla | £4 4/- | Igo Kekere | £3 |

## 'UROYSAN DRAGESS'

**Fun itọjutọbi fifo Apo Ile Itọ (Kidney Blinder) fun ọkunrin tabi obinrin bi awon amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu orunkun, Ibadi, Gige tabi riro eri itọ, tabi itọ jijo enia nọ i un rukurutu Pipọn aikoleri itọ te lakuregbe orunkun owo ẹsẹ Ejika wiwu tabi riro.**

Ara sisan, titobi aiko le gbe ra kọnkọn tabi kiskia didaju arinigbakugba ati oriṣiriṣi awọn aisan tabi amodi ba wọnyi ni egbogi ajẹbidan yi yio wo san lara rẹ ni kiakia ti alafia yio si de si ọ. Meji rẹ o si nj ilu Naijiria nitorina ṣọra ki awọn eleru tabi awọn oni rọbirọbi ma ta oriṣi miran ti ko ni lari fun ọ, maṣe gba rara! Owo rẹ jẹ Şile mẹfa abọ 6/6d owo Ọkọ sile kan ati abọ. (1/6d.)



NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square, Lagos

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street Lagos

GBANGBA DẸKUN! KEDERE BẸWO!! BI INA WỌLE OKUNKUN YIO PARADA IYỌN DAJU




BERE EGBOGI TUNTUN TI WỌN NPE NI:—

## "DROSELA"

Meji rẹ kosi ni igboro Ilu Eko tabi Nigeria lẹnu n Bi amodi ", IKỌ" ti ọjọ rẹ ti pẹ tabi ti o npọ rọbirọbi nkan bi ọdun kan iba jubẹ lọ, awọn egbogi se iwosan wọn n'a kakiri tabi ipolowo ni oriṣiriṣi ko le rẹ rara, ma fi owo rẹ şe ofo mọ.

Bere fun egbogi wọn ara ilu Faranşe ti nwọn npe gi "DROSELIA" ojulowo hauhaun atamatase oge fun Ikọ ẹgbẹ Ikọ Aiperi, Ikọ Awujgbọn Ikọ Awu egun Ikọ ọn fun, ikọ lile. Ikọ ti o mọ mu enia tiu ẹbẹ nigbakugba Itọ u " ifun wa (Lungs) tbiu ti o n mu enia ru pẹlu. Bi o ba dan Igo kan DROSELA wo Iwọ na yio ri iyatọ ninu ara rẹ ni kiakia Igba aya ti bi ọna ọfun rẹ ti o ma nho yio duro 'IKỌ" rẹ yio sisan patapata iwọ yio si ma jẹun daradara, iwọ yio si sun fọn fọn pelu, alafia de si ọ. Bere egbogi yi ati awọn oriṣiriṣi Egbogi Ikọ miran ni Ṣọbu awọn:-

WATERLOO MEDICINE STORES
8, Palmchurch Street Lagos
Phone 2287 Nigeria (Ọja Ita Faji)
ATI NI ṢOBU
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE BỌLA IBADAN
ADEDUN CHEMIST
14, Wakeman Street, Yaba.

# Ala Ati Itumọ Rẹ

James Ọlatunde, Iwo Ṣọra gidigidi ki oyun ma ba ṣe baję lara iya ... o rẹ tabi ẹnikan inu ile rẹ.

Ogundele Lawuyi, Ekiti: Iwọ yio gbọ ire ayọ kan lati ilu Okere laipẹ.

Isaha Adebayo:- Ijẹbu-Igbo:- Idaamu kan yio ba ọrẹ rẹ laipẹyi ṣugbọn nipase tirẹ ni nwọn yio ṣe ran ọrẹ na lọwọ.

Funayi Oseni, Okitipupa:- Oh n ... ere kan nbọ wa ṣẹlẹ si ọ iwọ yio si je ẹniti yio ni ifẹ si iṣẹ yio tẹ olorun ju ti atẹhin wa lọ.

Idowu Ọkanlawon Akinmọrin: Maṣe lọ si irinajo ninu ọsẹ yi ṣugbọn gbiyanju lati ma fi owo fun awọn alaini,

Timothy Ojẹkunle, Agẹ Arẹ: Iwọ yio g b e iyawo ki ọdun yi to pari tabi o fun ọmọbinrin kan l'oyun ṣugbọn maṣe kọ eyikeyi ninu rẹ ti o ba de bi bẹẹkọ iwọ yio k e abamọ gbẹhin.

Salawu Yisa Ilọrin: Owo aṣejere wa fun ọ ni asiko yi ṣugbọn wahala kan yio koju ọ yọju si ọ ra ma ṣe b ẹ r u igbẹhin adun.

Adekunlẹ Omọlolu Ibadan: Ọrọ idunnu ati ayọ kan wa niwaju rẹ, ṣugbọn Olọrun ko ti fi han ọ nibiti ọro ayọ na yio ti de si ọdọ rẹ.

Olugbile Ikoḷa..., O..ode: Ṣọra gidigidi ... i ... s ko yi nito ri ede yede ka ... yio ṣẹlẹ larin iwọ a ti awọn ọrẹ r... eyiti o le di ọrọ kotu.

Daniel Babalọla, Awẹ: Iwọ yi ... lọ si idalẹ kan laipẹyi owo aṣẹjere wa fun ọ, ṣugbọn ṣọra ki o le ba fi owo na ṣe ohunrere tabi ki owo na le duro mọ ọ lọwọ.

Tafa Salami, Igbo Ọra-: Iwọ yio di olowo ninu aiyerẹ ṣugbọn lati ẹhin odi ni o gbe ti ni owo na ki iṣẹ ninu ilurẹ.

AKIYESI:-

Iwọ na le fi ala tire ranṣẹ si,
Josefu Alala,
16, Bamgbọsẹ Street,
LAGOS.

## YE IRAWO RE WO

AQUARIUS (Jan 22 Feb 20) Ayọ ni fun o ni gbogbo ọjọ oni pelu ara lile ti ko si ohun kan lati damu rẹ

PISCES (Feb 21 Mar 20) Tun gbogbo nkan ti o ti ọsẹ berẹ ni irin ọna ti awọn enia yio fi ma sọrọ rẹ yio dara fun ọ

ARIES (Mar 21 April 20) Maṣe fi ọwọie ohunti tun kan ti i ... ọ ko şeri ero ti nwọn ngba si ọ nipe ki a le fun ọ l...run.

TAURUS (April 21 May 20) Aisan kekere kan yio ba ọje ṣugbọn alafia yio de ki o to to aṣ...ẹ.

GEMINI (May 21 July 21) Maṣe lo fi owo fa ijo gbọn w... ba ara rẹ jẹki o di gb ti i e ba ki o ma ba sina,

CANCER (June 22 July 22) O ni lati wa akoko pataki lati fi wa iṣẹ ṣe loni iwọ yio si ri iṣẹ ṣe.

LEO (July 23-Hug 22) Tẹlẹtẹlẹ gb gbo nkan dun lo ni ko nio ọ lo u ṣugbọn maṣe ṣe iru re loni.

VIRGO (Aug 23-Sept 23) Iwọ yio ri oju rere ọrẹ rẹ gba tobẹ ti iwọ ko ... i gbagbe ore ... a ti o ṣe fun lailai.

LIBRA (Sept 24-Oct 23) Obinrin gbajumọ kan yio ba ọ ṣọrọ fifẹ ... ra ẹni bi o ba mura si ọrọ na yio di iyawo rẹ.

SCORPIO (Oct 24-Nov 22) Iwa rere rẹ si awọn enia yio mu opolọpọ ire ati owo wa fun ọ.

SAGITTARIUS (Nov 23-Dec 21) Maṣe ba ẹni kan sọrọ asiri ki nwọn ma ba ṣe ... fofo rẹ pe ... r n.

CAPRICORN (Dec 22-Jan 21) Maṣe ṣe ... fin toto ni aṣeju ki a ma ba pe ọ ni eleke.

EGBOGI AWỌN ILU FARANSE

## TESSYDRE

Fun Ọmọ—Ọwọ ati Ọmọde gbogbo



Tessydre jẹ ojulowo egbogi hanhhaun ti meji iru fẹ bẹ kosi kakiri igboro ilu Naijiria fun itọju ọmọ ọwọ ati ọmọde lati le je ki wọn ma hu EHIN ẹnu wọn pẹlu irọrun laisi wahala rara tabi aiko le sun yala lọsan fun awọn iya wọn gbogbo Ọgọrun orişirişi egbogi bayi ni wọn npolowo sinu ẹrọ gbohungbohun ati sinu iwe kika lojojumọ ṣugbọn ko si ey ta le fi we egbogi Tessydre rara o, Ọlọgbọn di ori eja mu pupọ ninu awon ara ilu Saro ati awọn Agọnyin (GHANA) mọ egbogi yi dajudaju ... ni awọn si nlo fun awọn ọmọ ti wọn ba şeşẹ bi titi fi di nkan bi ọmọ ọdun mẹwa gbako. Kosi wahala tabi iyọnu Inu orun ọka ori aiperi ori inu iwọ osi fẹkun fẹkun ewo, kokoro ara lapalapa ara gbigbona igbẹ şişan gburu tabi sikolokun ninu are, sisu Inu kun nun aiorun ati orisirisi awon amodi tabi aisan ti o ma eyọ awon ọmọ ọwọ lẹnu nigba Ehin HIHU gbogbo Tessydre a ma mu ki ẹhin ẹnu ọmọ rẹ legbara gidigidi a ti ... san pẹlu.

Awọn ọmo t i o n l o egbogi yi ki saba ma sa rẹ rara tiwọn igbati nwọn ba ti nlo deede, ti otutu ki si le ri aye ati duro ni igbaiya wọn ti wọn njẹun daradara nwọn sun gbaduo pẹlu yio si je ki erigi san pẹlu.

NIGERIAN MEDICINE STORES
4 Tinubu Square Lagos

## Iwe Ilana Lọwọ Oşo Ati Aje

Iwe egbogi Ajẹbidan 25/- mejila £2
Iwe Ilana Ifa Iyanrin titẹ ati etutu rẹ pẹlu Iwosan 20/- mejila £2 5/-
Iwe Egbogi Awogba Arun meji 40/-
Turari isẹgun Ajẹ Oşo ati awọn abinijẹ O wa fun itaja pẹlu alakala Pangolo 10/- Paketi 2/- Ki işe ti ẹnu fifọn bi o ra ninu awọn ọjọ yi aabo ti o nipọ ni ile aiye ni yio wa lori rẹ ati awọn ẹbi rẹ.

Fi owo ranşe si
J O SHOYINKA
5 Alaba, Street
Odu abọrẹ Mushin.

